# LASU JOURNAL OF HUMANITIES
# (LASUJOH)

**VOL. 15, 2021 EDITION | ISSN: 978-274-384-4**

*A publication of:*

Faculty of Arts
Lagos State University, Ojo
Lagos, Nigeria.
Email: dean-arts@lasu.edu.ng

# LASU Journal of Humanities
## (LASUJOH)

Volume 15, 2021 Edition

© 2021 Faculty of Arts
Lagos State University, Ojo
Lagos, Nigeria

ISSN: 978-274-384-4

Produced by

**FREE ENTERPRISE PUBLISHERS LAGOS**

**HEAD OFFICE:** 50 Thomas Salako Street, Ogba,Ikeja, Lagos.
☎+234.814.1211.670.✉free.ent.publishers@gmail.com

**Editorial services, page composition and book design, and print production by**

FREE ENTERPRISE PUBLISHERS

## EDITORIAL BOARD

| | |
|---|---|
| Editor-in-Chief | Prof. Tayo Ajayi, Dean, Faculty of Arts, Lagos State University, Ojo, Lagos, Nigeria |
| Editor | Dr. Oseni Taiwo Afisi, Dept. of Philosophy, Lagos State University, Ojo |
| Associate Editor / Secretary, Editorial Board | Dr. Rasaq Thomas, Dept. of Foreign Languages, Lagos State University, Ojo |
| Business Manager | Dr. Abayomi Bello, Dept. of Theatre Arts and Music, Lagos State University, Ojo |
| Managing Editor | Dr. Titilayo Onadipe-Shalom, Dept. of African Languages, Literatures & Communication Arts |
| Members | Dr. Adewunmi Falode, Dept. of History & Int'l. Studies, Lagos State University, Ojo |
| | Dr. Adepeju Johnson Bashua, Dept. of Religions & Peace Studies, Lagos State University, Ojo |
| | Dr. Ayo Ayodele, Dept. of English, Lagos State University, Ojo |
| | Dr. Maruf Animashaun, Dept. of Foreign Languages, Lagos State University, Ojo |
| | Dr. Oseni T. Afisi, Dept. of Philosophy, Lagos State University, Ojo |
| | Dr. Ahmed Adesanya, Dept. of African Languages, Literatures & Communication Arts, Lagos State University, Ojo |
| | Prof. Sola Fosudo, Dept. of Theater Arts & Music, Lagos State University, Ojo |

## EDITORIAL CONSULTANTS

| | |
|---|---|
| Prof. Ihuah Aloysius Shaagee | Benue State University, Makurdi Benue State |
| Prof. I.S. Aderibigbe | University of Georgia, Athens, Georgia USA |
| Prof Rauf Adebisi | Ahmadu Bello University, Zaria Kaduna State |
| Prof. Gbenga Ibileye | Federal University, Lokoja Kogi State |
| Prof. Bode Omojola | Mount Holyoke College, South Hadley, Massachusetts, USA |
| Prof. Emmanuel DanDaura | Nasarawa State University, Keffi Nasarawa State |
| Prof. Antonia Schleicher | Indiana University, Bloomington Indiana, USA |
| Prof. Toyin Falola | University of Texas at Austin, Texas, USA |
| Prof. Mashood Baderin | School of Law University of London, Russell Square London, UK |

# SUBMISSION OF ARTICLES

(Published by the Faculty of Arts, Lagos State University, Ojo, Lagos, Nigeria), the LASU Journal of Humanities encourages submissions from a variety of theoretical standpoints and from different disciplines—especially those that traditionally belong to the all-encompassing "Faculty of Arts" including, however, other areas with which the Faculty has affiliation: anthropology, cultural studies, folklore, media studies, popular culture, communication, sociology and political science.

## GUIDELINES FOR AUTHORS

- **Articles**

Authors should submit research articles of (maximum) 10-20 A4 pages, double spaced, 12-point Times New Roman type, in accordance with the MLA or APA style, and include an abstract of not more than 100 words and a "Works Cited" section. Authors should email their articles as Microsoft Word (version 97-2000 or later) format attachment to: dean-arts@lasu.edu.ng

- **Journal Flyer/Call For Paper:**

Every article for publication must be accompanied by a processing fee of Ten Thousand Naira only in cash or by cheque payable to the Faculty Wema Bank Account: LASU FAC Arts Research, Publications & Conference Account Number: 0240791717. Please request a receipt or written acknowledgement for all such payments..

- **Illustrations**

If an article is selected for publication, electronic copies of accompanying illustrations, photographs and diagrams must be provided, as well as all necessary captions. Permission to publish images must be secured by the author. Uncompressed JPEG/PDF file (300 dpi resolution) is the preferred format for all electronic copies. Electronic copies must be sent as e-mail attachments to: dean-arts@lasu.edu.ng

- Warning—Footnotes are absolutely prohibited

Journal Address: LASU Journal of Humanities
c/o The Dean, Faculty of Arts, Lagos State University, Ojo
Lagos, Nigeria. e-mail: lasujournalofhumanities@lasu.edu.ng

- Subscription—The Journal is published twice annually although submissions are accepted throughout the year

# Contributors

1. Adeniyi, Sakiru
Dept. of Yoruba
School of Languages
Adeniran Ogunsanya College of Education
Otto/Ijanikin, Lagos

2. Afolayan, Bosede Funke
Dept. of English
University of Lagos
Lagos

3. Afisi, Oseni Taiwo
Dept. of Philosophy,
Lagos State University,
Ojo, Lagos.

4. Animashaun, Maruf
Dept. of Foreign Languages
Lagos State University,
Ojo, Lagos

5. Àkànmú, Dayọ̀
School of Languages
Adeniran Ogunsanya College of Education
Oto/Ijanikin, Lagos State, Nigeria

6. Amore, Kehinde Pedro
Dept. of English
Tai Solarin University of Education
Ijagun, Ijebu-Ode, Ogun State.

7. Amosu, Kehinde Olorunwa
Dept. of Philosophy,
Lagos State University
Ojo, Nigeria.

8. Amusan, Kayode Victor
Dept. of English,
University of Ibadan
Ibadan

9. Baruwa, Olaide Abibat
Dept. of Public Relations and Advertising
Lagos State University

10. Bello, Abayomi Omotoyosi
Dept of Theatre Arts & Music
Lagos State University
Ojo

11. Komolafe, Hezekiah Deji
Dept. of Religions,
University of Ilorin, Ilorin

12. Macaulay-Adeyelure, Olawunmi
Dept. of Philosophy,
Lagos State University, Nigeria.

13. Makinde, Solomon Olarenwaju
Dept. of Language, Arts & Social Science Education,
Lagos State University
Ojo, Lagos, Nigeria.

14. Musa, Haruna
Dept. of Foreign Languages
Lagos State University

15. Olawuyi, Ebenezer Adebisi
Dept. of Communication & Language Arts
University of Ibadan
Nigeria

16. Oniyide, Daud
Dept. of Foreign Languages
Lagos State University,
Ojo, Lagos

17. Saibu, Israel Abayomi
Dept. of History & International Studies
Anchor University
Lagos, Nigeria

18. Thanny, Noeem Taiwo
Dept. of Public Relations and Advertising
Lagos State University

19. Thomas, Razaq
Dept. of Foreign Languages
Faculty of Arts
Lagos State University, Ojo

20. Yekini-Ajenifuja, Isaac A.
Dept. of Theatre Arts and Music
Lagos State University, Ojo

# Contents


1 Democracy and Good Governance in Africa: Beyond the Myths and Illusions —Amosu, Kehinde Olorunwa . . . . . . . . 1

2 Taxonomy of Sound in Islamic Religious Practice among the Ansar-ud-Deen Society of Nigeria—Yekini–Ajenifuja, Isaac, PhD. . . . . . . . 10

3 Osofisan's Mythopoetic Reimaginings of the Gods and its Implications for Contemporary Postcolonial Discourse—Afolayan, Bosede Funke . . . . . . . . 20

4 On the Socially Constructed Racial Categories of "White" and "Black": An Abolitionist's Case—Afisi, Oseni Taiwo & Macaulay-Adeyelure, Olawunmi . . . . . . . . 33

5 Phoneme /L/ and its Allophones in the Southeast Yorùbá: An Optimality Theory Account —Adeniyi, Sakiru . . . . . . . . 43

6 Influence of Family Communication on Adolescent Students' Learning Processes in Lagos, Nigeria—Thanny, Noeem Taiwo & Baruwa, Olaide Abibat . . . . . . . . 54

7 The Yoruba Film as an Exploration of Yoruba Culture, Worlds of the Living, the Dead and the Yet Unborn—Amore, Kehinde P., PhD, Amusan, Kayode V. & Makinde, S. Olarenwaju . . . . . . . . 65

8 Christianity and Child Training: An Appraisal of Proverbs 22:6 —Komolafe, Hezekiah Deji, PhD . . . . . . . . 75

9 Dayo Oyedun's Compositional Style: An Analysis of *Cathedral Anthem I* —Bello, Abayomi Omotoyosi, PhD . . . . . . . . 87

10 Social Security: A Panacea for the Socioeconomic Challenges in Postcolonial Nigeria —Saibu, Israel Abayomi . . . . . . . . 95

11 China through the Lens of Nigerian Media—Olawuyi, Ebenezer Adebisi . . . . . . . . 107

12 Àmúlò Ọ̀rọ̀ Àwàdà nínú iṣẹ́ Adébáyọ̀ Fálétí—Àkànmú, Dayọ̀ PhD . . . . . . . . 128

13 Politique, Enseignement et Statut du Français au Nigéria : Trace d'une Contrainte Traductique—Thomas, Razaq, PhD . . . . . . . . 140

14 Vision Heroique de Salimata dans les Soleils des Independances d'Ahmadou Kourouma —Musa, Haruna . . . . . . . . 150

15 قضية الطبع والصنعة في ضوء النقد الأدبي:دراسة موسعة —Animashaun, Maruf. . . . . 160

16 التّعابير اليورباوية المتداولة من السّياق القرآني: دراسة تناصية —Oniyide, Daud . . . . . . . 178

# 12

# Àmúlò Ọ̀rọ̀ Àwàdà nínú iṣẹ́ Adébáyọ̀ Fálétí

*Àkànmú, Dayọ̀ PhD*


## Àṣamọ̀

*Ọ̀rọ̀ àwàdà jẹ́ kókó kan gbòógì tí a kò le fọwọ́ yẹpẹrẹ mú nínú iṣẹ́ ọnà nítorí ipa pàtàkì tí ó ń kó nínú ìyànjú àwọn òǹkọ̀wé, òṣèré àti àwọn oníròyìn àti ìwúlò rẹ̀ fún ìdàgbàsókè àti ìrọ̀rùn àwùjọ àgbáyé. Ìran aláwàdà tàbí ìran tí àwàdà ṣíṣe wà nínú ẹ̀jẹ̀ rẹ̀ ni ìran Yorùbá jẹ́ àti pé bí ọjọ́ àbókí ti pẹ́ tó nínú obì jíjẹ ni ọjọ́ àwọn Yorùbá náà ṣe pẹ́ nínú àwàdà ṣíṣe. Síwájú àkókò yìí, ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọmọ Yorùbá tí ó jẹ́ oníṣẹ́ ọnà tàbí alátinúdá bíi Moses Adéjùmọ̀ (Bàbá Sàlá) àti àwọn tí ó wá lẹ́yìn rẹ̀, ni ó ti fi ọ̀rọ̀ àwàdà tàbí ọ̀rọ̀ apanilẹ́rìn-ín buta nínú iṣẹ́ ọnà wọn. Ní ti iṣẹ́ ọnà ìwé kíkọ, ọ̀rọ̀ àwada dàbí ẹ́njín-ìn-nì ọkọ̀ èyí tó jẹ́ pé ọkọ̀ kò ní ṣe é wà tí kò bá sí nínú rẹ̀. Bí kò bá sí ọ̀rọ̀ àwàdà nínú ìwé alátinúdá, ìwé náà kò ní ṣe é kà ní àkàgbádùn. Ìyànjú láti rí i bí Adébáyọ̀ Fálétí ṣe mú ọ̀rọ̀ àwàdà tàbí ọ̀rọ̀ apanilẹ́rìn-ín ní ọ̀kúnkúndùn nínú àwọn ìwé eré onítàn, ìwé ìtàn àròsọ àti ìwé ewì rẹ̀ ni ó ṣokùnfà bébà yìí kí á le mọ iṣẹ́ tí Fálétí ń fi ọ̀rọ̀ àwàdà tàbí ọ̀rọ̀ apanilẹ́rìn-ín jẹ́ fún àwùjọ nínú àwọn ìwé rẹ̀. Ìlànà ìṣọwọ́loèdè ní a gùn lé fún ìtúpalẹ̀ ọ̀rọ̀ àwàdà tó jẹ jáde nínú àwọn iṣẹ́ Fálétí kí á lè mọ bí ó ṣe ṣe àgbékalẹ̀ àwọn ọ̀rọ̀ àwàdà àti bí ó ṣe lo ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ èrò rẹ̀ láti wá ojútùú sí oríṣìí àdojúkọ ẹ̀dá nílé ayé nípa ìṣàmúlò ọ̀rọ̀ apanilẹ́rìn-ín.*


***Kókó ọ̀rọ̀:*** *ọ̀rọ̀ apanilẹ́rìn-ín/àwàdà, iṣẹ́ ọnà Fálétí, Yorùbá, ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ èrò, ìṣọwọ́loèdè*


## Abstract

*Comic or laughter-induced expressions are universal phenomena that cannot be underestimated in any literary work based on their vital role which usually compliment efforts of the playwrights, artists and communication experts, and their significance for convenience of the society at large. It is believed that the Yorùbá people are from the lineage of a tribe that is genetically comical to the extent that their utterances usually ignite laughter when interracting with others. In the past, several Yorùbá literary scholars, playwrights, authors and creative artists have made fortune from the use of laughter induced expressions in their different creative endeavours. In creative writings*

*like play, prose and poetry, comic or laughter induced expressions are comparable to the vehicle engine without which the vehicle cannot move. Without laughter induced expressions, creative efforts of the playwrights and other literary personnel become an exercise in futility as readers are likely to find such creative work very boring. Attempt to investigate how Adébáyọ̀ Fálétí used laughter induced expressions in his works is what this paper addressed with a view to knowing issues expressed with these expressions and messages conveyed with them to the society. Stylistic Analytical Method is adopted for the interpretation of laughter induced expressions in order to unveil how these expressions are established and how Faleti's philosophical belief is at play in offering solution to various human challenges with the use of comic or laughter induced expressions.*

*Keywords: laughter induced expressions, stylistic analysis, philosophy, creative writing, Adébáyọ̀ Fálétí, Yorùbá*

## Ìfáàrà

Kò sí ibi tí a kìí tí dáná alẹ́ ní ọ̀rọ̀ apanilẹ́rìn-ín jẹ́, iná ọbẹ̀ yóò wulẹ̀ dùn ju ara wọn lọ ni. Káríayé ni ọ̀rọ̀ àwàdà jẹ́ nítorí ipa pàtàkì tí ó ń kó nínú ìyànjú àti iṣẹ́ àwọn gbogbo oníṣẹ́ ọnà pátápátá àti ní àwùjọ ọmọ adáríhurun. Kò sí ọmọ ẹ̀dá kan tí ó dá pé tí kì í ṣe àmúlò ọ̀rọ̀ apanilẹ́rìn-ín yálà kí ó mọ̀-ọ́n-mọ̀ lò ó tàbí kí ó kàn déédé já bọ́ láti ẹnu rẹ̀. Ọ̀rọ̀ àwàdà náà ni a pè ní ọ̀rọ̀ apanilẹ́rìn-ín nínú bébà yìí nitorí pé ọ̀rọ̀ tó bá lè mú ẹ̀rín wá náà lè fa àwàdà àti pé ẹ̀rin ni àbájáde àti àyọrísí àwọn méjèèjì. Ìdí ni pé bí kò bá sí àwàdà tàbí èròjà ẹ̀rín nínú ìsọ kan, ẹ̀rín kò lè wáyé. Lóòtítọ́, ọ̀rọ̀ apanilẹ́rìn-ín kì í ṣe ara ẹ̀yà lítíréṣọ̀ kankan ṣùgbọ́n kí á tó lè ṣe àgbékalẹ̀ lítíréṣọ̀ tàbí iṣẹ́ ọnà kan ní àṣeyege, a gbọ́dọ̀ ṣe àmúlò ọ̀rọ̀ apanilẹ́rìn-ín. Ìdí ni pé, ohun tí ó jẹ lítíréṣọ̀ lógún ni ìdárayá nínú èyí tó jẹ́ pé ọ̀rọ̀ apanilẹ́rìn-ín gan-an ni ó fi ṣe àtẹ̀gùn. Abájọ tí Fálétí nínú Ọlátúnjí (1982) ṣe sọ nínú ọ̀rọ̀ rẹ̀ nípa àwọn akéwì ìbílẹ̀ pé.

> Nǹkan tí àwọn akéwì ìṣẹ̀ǹbáyé tiwa ń ta sí ni *àwàdà* tí wọ́n lè ṣe, ká túra ká, ká *para wa lẹ́rìn-ín,* ká gbọnwọ́ ọ̀fọ̀ dànù, kì í ṣe wí pé ẹ̀kọ́ tí wọ́n ń kọ́ni. Bí bẹ́ẹ̀ kọ́, ewì ó di nǹkan kokooko tí àwọn ènìyàn ò ní fẹ́ gbọ́.

Tí a bá gùnlé ọ̀rọ̀ Fálétí òkè yìí, a lè sọ pé kì í ṣe ewì nìkan ni yóò di nǹkan kokooko tí àwọn ènìyàn kò ní nífẹ̀ẹ́ sí láti gbọ́; bí kò bá sí ọ̀rọ̀ apanilẹ́rìn-ín tí ó lè mú ìdárayá wá nínú rẹ̀, gbogbo iṣẹ́ ọnà tàbí lítíréṣọ̀ Yorùbá gan-an ni yóò di nǹkan kokooko. Irú nǹkan wọ̀nyí ni a lérò pé ó jẹ Fálétí lógún tí ó fi mú ọ̀rọ̀ àwàdà tàbí ọ̀rọ̀ apanilẹ́rìn-ín ní ọ̀kúnkúndùn nínú ọ̀pọ̀lọpọ̀ iṣẹ́ rẹ̀; èyí gan-an ni ó mú kí Fálétí ta gbogbo àwọn òǹkọ̀wé ẹgbẹ́ rẹ̀ yọ. Gbogbo atótómu tí a ṣe lórí ọwọ́ tí Fálétí fi mú ọ̀rọ̀ apanilẹ́rìn-ín nínú àwọn iṣẹ́ rẹ̀ ni ó ṣokùnfà ìdí pàtàkì tí a fi fẹ́ fi ojú ìmọ̀ ìṣọwọ́loèdè tú iṣu dé ìsàlẹ̀ kòkò àwọn ọ̀rọ̀ apanilẹ́rìn-ín tí ó ṣú yọ nínú iṣẹ́ rẹ̀ kí a lè mọ bí ó ṣe ń ṣe àmúlò ọ̀rọ̀ àwàdà fún ìgbádùn àwọn òǹkàwé rẹ̀.

## Èrè ìdí bébà yìí

Ohun tí ó ṣokùnfà bébà yìí ni àkíyèsí wa lórí ọ̀kan-ò-jọ̀kan iṣẹ́ Adébáyọ̀ Fálétí èyí tí àbájáde rẹ̀ fi òkodoro ọ̀rọ̀ hàn pé ọ̀rọ̀ apanilẹ́rìn-ín tàbí ọ̀rọ̀ àwàdà sodo sínú iṣẹ́

rẹ̀. Kì í ṣe pé ìṣọwọ́ kọ ìtàn nìkan ni ó mú wa lọ́kàn bí kò ṣe àwọn ọ̀nà tí ó gbà láti ṣe àmúlò àwọn ọ̀rọ̀ apanilẹ́rìn-ín nínú àgbékalẹ̀ iṣẹ́ rẹ̀.

Nínú ọ̀pọ̀lọpọ̀ iṣẹ́ rẹ̀, ní pàtàkì jùlọ, àwọn iṣẹ́ rẹ̀ tí ó gbọ̀n'ni lẹ́kún tàbí tí ó mú ìbànújẹ́ wá; Fálétí ṣe àgbékalẹ̀ àwọn kókó irú iṣẹ́ báyìí ní ọ̀nà tí ó panilẹ́rìn-ín tí ó sì pa ìbànújẹ́ rẹ́. Ju gbogbo rẹ̀ lọ, ohun tí ó jẹ wá lógún jùlọ lórí iṣẹ́ yìí ni bí Fálétí ṣe ń ṣe àmúlò àwọn ọ̀rọ̀ apanilẹ́rìn-ín àti bí ó ṣe ń fi ojú ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ èrò wo àwọn ọ̀rọ̀ apanilẹ́rìn-ín nínú iṣẹ́ rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí òǹkọ̀wé tí ó fẹ́ fi ọ̀rọ̀ apanilẹ́rìn-ín rán iṣẹ́ sí àwùjọ tàbí fi dá wọn lárayá.

### Ẹ̀rín àti ọ̀rọ̀ apanilẹ́rìn-ín

Ẹ̀rín àti ọ̀rọ̀ apanilẹ́rìn-ín jẹ́ ohun àdámọ́ ọmọ ẹ̀dá tí a kò le fi ọwọ́ rọ́ sẹ́yìn láwùjọ Yorùbá. Bí ẹ̀rín àti ọ̀rọ̀ apanilẹ́rìn-ín ṣe ṣe pàtàkì tó gẹ́gẹ́ bí ọ̀kan lára èròjà ọ̀nà ibánisọ̀rọ̀, ọwọ́ yẹpẹrẹ ni àwujọ wa fi mú wọn nípa ti àkọsílẹ̀ tàbí kíkọ́ gẹ́gẹ́ bí ìmọ̀ kan. Ìdí nì yí tí kò fi bẹ́ẹ̀ sí púpọ̀ nínú àwọn onímọ̀ Yorùbá tí ó kọ nǹkan gíríkì nípa ẹ̀rín. Atótónu àwọn onímọ̀ ilẹ̀ òkèèrè bíi Askenasy (1987), Berlyne (1969), Chapman (1976), Darwin (1972), Hirson (1995), Provine (1996), Ruch (1993), Ruch and Ekman (2001) lórí ẹ̀rín ní èdè Gẹ̀ẹ́sì ni pé:

> People laugh in different situation and various emotional states, such as joy, affection, amusement, cheerfulness, surprise, nervousness, sadness, aggression, triumph (pleasure in another's misfortune).
>
> [Ọmọ èèyàn a máa rẹ́rìn-ín ni oríṣìíríṣìí àáyè àti ipò tí ó wọ̀ wọ́n lára bíi ayọ̀, Ìfẹ́, ìdùnnú, ìyàlẹ́nu, ìkáyàsókè, ìbànújẹ́ àti ìṣẹ́gun èyí tí ó dá lórí fifi orí burúkú tí ó dé bá ẹlòmíràn yọ̀ wọ́n.]

Ẹ̀rín a máa jẹ jáde nípa ohun tí a fi ojú rí tàbí ohun tí a fi etí gbọ́ àti ohun tí a fi ẹnu sọ. Nígbà tí a bá fi etí gbọ́ tàbí fi ẹnu sọ ohun tí ó pa wá lẹ́rìn-ín, dájúdájú, ọ̀rọ̀ apanilẹ́rìn-ín ni a ṣe àmúlò rẹ̀. Ọ̀rọ̀ apanilẹ́rìn-ín yìí gan an ni a fẹ́ yẹ̀ wò nínú iṣẹ́ Adébáyọ̀ Fálétí kí á lè mọ ọ̀gangan ibi tí ó ti lò wọ́n, bí ó ṣe lò wọ́n, iṣẹ́ tí ó ń fi wọ́n rán sí àwùjọ àti ìwúlò wọn ní àwọn ọ̀gangan ibi tí ó ti ṣe àfihàn ipò ìbànújẹ́ nínú iṣẹ́ rẹ̀.

### Ẹ̀yà ẹ̀rín

Oríṣìí ẹ̀yà ẹ̀rín ni ó wà àti pé ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn máa ń wáyé nípasẹ̀ ọ̀gangan ààyè tàbí ipò ìṣẹ̀lẹ̀ tí ó bí wọn. A lè rí àpẹẹrẹ wọn báyìí:

a. Ẹ̀rín a jẹmọ́ ìṣèlú—Ẹ̀yà ẹ̀rín yìí jẹ́ èyí tí a máa ń lò láti fi ẹ̀hónú tí kò mú ìpalára wá hàn sí ìwà jíjẹ gàba léni lórí tàbí fifi ọwọ́ ọlá gbáni lójú nínú ọ̀rọ̀ ìṣèlú. Èyí tí ó tún farapẹ́ àpẹẹrẹ oríkí tí a fún ẹ̀yà ẹ̀rín yìí ni ìṣẹ̀lẹ̀ nínú ìtàn Yorùbá láyé ìṣèjọba ọ̀kan lára àwọn Aláàfin tó ti jẹ ọba nílùú Ọyọ́ níbi tí àwọn eégún Alárinjò ti lo àwòrán ìṣeré wọn ní gbàgede láti ṣe àpèjúwe ìwà àbùkù, tí ó bu ọba kù èyí tí Kúdẹ̀ẹ́fù, ẹrú ọba ń wù nípa kíkó patíẹ bo àwọn ènìyàn àti Ọba pàápàá láìbìkítà. Ìgbà tí ó kó patíẹ bo Aláàfin fúnra rẹ̀ ni àwọn ènìyàn tí ó ń wòran pariwo báyìí pé: "Kúdẹ̀ẹ́fù! Ẹrú ò m'ọba."

b. Ẹ̀rín a jẹmọ́ àyè, ipò tàbí ìṣòro kan—Irú ẹ̀rín yìí dá lórí àfọwọ́fà ìṣòro tí ọmọ

ẹ̀dá lè kó ara rẹ̀ sí èyí tí ọ̀nà àbáyọ sí irú ìṣoro bẹ́ẹ̀ máa ń nira gan an. Bí àpẹẹrẹ, nínú ọ̀kan lára àwàdà olóògbé Moses Ọláìyá (Bàbá Sàlá) tí ó pè ní "*À bó o yó*" níbi tí ó ti kó ipa agbẹjọ́rò tí ó ń fi ìgboyà ka àyọlò láti inú Bíbélì lórí ìjà ilẹ̀ bí ìgbà tó jẹ́ pé ìwé òfin orílẹ̀ èdè kan ni. Gẹ́lẹ́ tí Bàbá Sàlá sọ pé "*ti Olúwa ni ilẹ̀ àti ohun gbogbo tí ó wà lórí rẹ̀*" ni adájọ́ kò ka ọ̀rọ̀ Bàbá Sàlá kún nǹkankan, ó bú u fún ìwà àrékérekè àti fifi ìwà ọ̀daràn ṣe ẹ̀fẹ̀ ṣùgbọ́n Bàbá Sàlá kò ka ọ̀rọ̀ adájọ́ sí nǹkan kan; ìyànjú láti wí àwíjàre ni ó mú kí Bàbá Sàlá tún lo àyọlò mìíràn láti inú ìwé Matthew kí ó lè dá adájọ́ lẹ́kun wí pé "*ènìyàn kò gbọdọ̀ dá ẹnikẹ́ni lẹ́jọ́ kí á má baà dá òun náà lẹ́jọ́.*" Nígbẹ̀yìn, Bàbá Sàlá pàdánù ẹjọ́ náà.

c. Ẹ̀rín tí òkodoro tàbí òye rẹ̀ kò lọ tààrà—Irú ẹ̀rín yìí jẹ́ èyí tí àgbékalẹ̀ ìṣẹ̀lẹ̀ rẹ̀ wáyé láìrò tẹ́lẹ̀ lọ́nà tí òye tàbí ọgbọ́n inú rẹ̀ kò lọ tààrà. Bí àpẹẹ̀rẹ́, obìnrin kan tí kò ní ìmọ̀ mọ̀-ọ́n-kọ, mọ̀-ọ́n-kà dorí ìwé àtìgbà-dé-gbà tí olóògbé Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ wà nínú rẹ̀ kodò. Nípa àìmọ̀kan obìnrin yìí, ó bẹ̀rẹ̀ sí ní ka ìwé náà ní àtoríkòdì pẹ̀lú ariwo ńlà̀: "Hún ùn! Awólọ́wọ̀, ọ̀kùnrin ogun. Bí ó bá wù ú, á fi ẹsẹ̀ méjéèjì rìn, Bí ó bá sì tún wù ú, á fi orí rẹ̀ rìn." Lóòótọ́, Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ jẹ́ akọni ènìyàn nígbà ayé rẹ̀ ṣùgbọ́n gbígbé ìwé ìròyìn àtìgbà-dégbà náà ní àtoríkòdì ni ó fa ẹ̀rín tí òye tàbí òkodoro rẹ̀ kò lọ tààrà àti pé àtoríkòdì àwòrán Awólọ́wọ̀ yìí tún ṣe àfihàn akọni àti àkàndá èèyàn tí Awólọ́wọ̀ jẹ́. Lọpẹ́lọpẹ́ arákùnrin tí òun náà ń kàwé ìròyìn lẹ́gbẹ̀ẹ́ obìnrin náà ni ó ṣàlàyé fún un pé Awólọ́wọ̀ kò fi orí rìn àti pé àtoríkòdì ni obìnrin náà ń ka ìwé tirẹ̀.

d. Ẹ̀rín tí a fi ń tẹ́mbẹ́lú, yẹpẹrẹ tàbí yẹ̀yẹ́ ènìyàn -- irú ẹ̀rín báyìí máa ń wáyé nígbà tí ẹni tí a rò pé ó ti tán fún, tí kò sì ní agbára kankan mọ́ tàbí tí gbogbo ipá rẹ̀ pin ṣùgbọ́n tí ọ̀nà àbáyọ wá dé fún un lójijì. A rí àpẹẹrẹ èyí nínú *Ogun Àwítẹ́lẹ̀* níbi tí olú ọdẹ ti yìnbọn fún olórí àwọn ìgárá ọlọ́ṣà lọ́pọ̀lọpọ̀ ìgbà láìtu irun kankan lára rẹ̀ títí ó fi bú sẹ́rìn-ín báyìí pé: "Ǹjẹ́ ọde o kò ha yára máa kó sínú ìbọn rẹ, à bí kín ni ó tún kù, nítorí lónìí ni n ó jẹ́wọ́ ilé fún ọ, n ó fi hàn ọ́ pé eyín mú ju ọ̀bẹ lọ." Ó yẹ kí a fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé nínú iṣẹ́ ọnà, àwọn oníṣẹ́ ọnà máa ń lo ọ̀rọ̀ apanilẹ́rìn-ín lóríṣìíríṣìí ọ̀nà nínú àtinúdá wọn. Adébáyọ̀ Fálétí gan-an kò gbẹ́yìn nínú ṣíṣe èyí ati pe ọ̀pọ̀lọpọ̀ iṣé àtinúdá rẹ̀ bíi ewì, eré onítàn àti àwọn tí ó kù ni ó ti lo àwọn ọ̀rọ̀ tí ó ń dẹ́rìn-ín pa ènìyàn. Àwọn àpẹẹrẹ ẹ̀yà ẹ̀rín tí a mẹ́nu bà yìí jẹ́ kí á mọ̀ pé àwọn ọ̀rọ̀ apanilẹ́rìn-ín máa ń ṣiṣẹ́ ní oríṣìíríṣìí ọ̀nà tàbí àyè kan ní àwujọ ọmọ èèyàn.

## Orísun Ẹ̀rín tàbí Ọ̀rọ̀ Apanilẹ́rìn-ín Nínú Iṣẹ́ Fálétí

Orísun ẹ̀rín tàbi òrọ̀ apanilẹ́rìn-ín wà lọ́wọ́ bí ẹni tí ó ń ṣàmúlò rẹ̀ ṣe dáńgájíá tó nínú ìṣàmúlò èdè. Fún ìdí èyí, a lè sọ pé àwọn nǹkan tí a mẹ́nu bà nísàlẹ̀ yìí jẹ́ orísun ẹ̀rín tàbí ọ̀rọ̀ apanilẹ́rìn-ín nínú iṣẹ́ Fálétí.

### 1. Àfiwé

Àfiwé tó jẹ́ ọ̀kan lára orísun ẹ̀rín tàbí ọ̀rọ̀ apanilẹ́rìn-ín nínú iṣẹ́ Adébáyọ̀ Fálétí lè jẹ́ Àfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ́ tàbí àfiwé tààrà. A máa ń lo mẹ́táfọ̀ gẹ́gẹ́ bí atọ́ka ìtumọ̀ tí ó jinlẹ̀ yàtọ̀ sí ti ìtumọ̀ léréfèé. Àwọn onímọ̀ bíi Táíwò (2017), Ọlátẹ́jú (2005) àti Ọlábọ̀dé (1981) ri mẹ́táfọ̀ gẹ́gẹ́ bí ọ̀nà tí à ń gbà láti yí òye ohun kan padà sí òmíràn lọ́nà tó jẹ́ pé òye ohun tí à ń yí padà yóò dá dúró gẹ́gẹ́ bí ìṣẹ̀dá ọ̀rọ̀ tí ó yapa sí ti àkọ́kọ́. Nínú bébà yìí, Fálétí ṣe àmúlò ọ̀pọ̀lọpọ̀ mẹ́táfọ̀ gẹ́gẹ́ bí ọ̀rọ̀ apanilẹ́rìn-ín. Bí àpẹẹrẹ, nínú ewì *Ìgbéyàwó Kan Ní Ìletò Wa*, Fálétí fi mẹ́táfọ̀ tí ó pa ènìyàn lẹ́rìn-ín ṣe àpèjúwe gẹ̀gẹ̀ Àkàndé nígbà tí ó ń jó báyìí:

> B'ípàkọ́ ti ń fì dùgbẹ̀ lẹ́hìn *Òrúbandú* tí ḿ bẹ lọ́rùn a sì yọ síwájú bọbọbọ (*Ìgbéyàwó Kan Ní Ìletò Wa II* 179-188).

Nínú àpẹẹrẹ yìí, "*òrúbandú"* ni mẹ́táfọ̀ tí ó pani lẹ́rìn-ín nítorí pé ó bá wa lójijì, ó sì tún ṣe àjèji sí wa gẹ́gẹ́ bí ìsọ tí ó pàkíyèsí wa sí ara rẹ̀ èyí tí ènìyàn kò le tètè ronú sí. A lo mẹ́táfọ̀ yìí láti ṣàpèjúwe títóbi gẹ̀gẹ̀ Àkàndé èyí tí ó ṣ'ẹni ní kàyééfì.

Oríṣìí àfiwé kejì ni "àfiwé tààrà" èyí tí Ọlátúnjí (1984:55) ṣe àpàjúwe rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí "fifi ohun méjì tí ó jọ ara wọn wé ara." Àfiwé tààrà máa ń ya àwòrán ohun méjì tí à ń ṣe àpèjúwe wọn sí ọkàn wa lọ́nà tó yè kooro. Nínú ìyànjú Fálétí láti lo àfiwé tààrà fún ìpanilẹ́rìn-ín, ó máa ń lò ó fún gbígbé oríyìn fún èèyàn tàbí nǹkan, bíbú ènìyàn, ṣíṣe àfihàn àti àlàyé kíkún nípa nǹkan ni. A lè rí àpẹẹrẹ, èyí náà nínú ewì "*Ọjọ́ Ìláyẹ̀fun"* níbi tí Láàlà ti darapọ̀ mọ́ Ṣàngódòkun ọ̀rẹ́ rẹ̀ láti lá èlùbọ́ kí àwọn àna Ṣàngódòkun má ba à mọ̀ pé ó ní àmóódi. Nípa ìṣàmúlò àfiwé tààrà, Fálétí ṣe àpèjúwe Ṣàngódòkun bí ó ṣe ń lá èlùbọ́ báyìí:

> Ibẹ̀ nìyá ìyàwó ti bá Ṣàngódòkun tí ń jèlùbọ́ èkùkù *bi* àgùtàn tí ń lánu mọ́rán *bí* awúrẹ́ jewé ata. (*Ọjọ́ Ìláyẹ̀fun II*, 145-147).

Ìṣàmúlò àfiwé tààrà nínú àpẹẹrẹ ewì òkè yìí kò lè sàìmápanilẹ́rìn-ín, ní pàtàkì jùlọ, ẹni tí ó bá ti rí ibi tí ewúrẹ́ ti ń jẹ ewé ata rí. Irú àfiwé yìí máa ń ya àwòrán ìṣẹ̀lẹ̀ tí a ti rí rí sí ọkàn ẹni ni. Fálétí fi ọ̀rọ̀ àfiwé tààrà tí ó pa èèyàn lẹ́rìn-ín yìí ṣe àfiwé ìjọra bí Ṣàngódòkun ṣe ń lá èlùbọ́ sí ti ewúrẹ́ tí ó ń jẹ ewé ata.

### 2. Àsọrégèé

Àsọrégèé ni kí á ṣe ìròyìn ìṣẹ̀lẹ̀ kan ju bí ó ṣe ṣẹlẹ̀ lọ. A máa ń bù kún ìṣẹ̀lẹ̀ tàbí kí a sọ pé ohun tí kò lè ṣeéṣe kí ó ṣẹlẹ̀ tàbí wáyé rárá ṣẹlẹ̀ (Ọláwúwo àti Atọ́lágbé 2011:96). Lọ́pọ̀lọpọ̀ ìgbà, Fálétí máa ń ṣe àmúlò àsọrégèé bíi ọ̀rọ̀ apanilẹ́rìn-ín nínú àwọn iṣẹ́ rẹ̀ láti fi dẹ́rìn-ín pa àwọn òǹkàwé rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ó ṣe hàn nínú "*Ọmọ Olókùn Ẹṣin"* níbi tí Àjàyí ti ń ṣàlàyé bí àwọn ará ìlú rẹ̀ ṣe wà nínú ìgbèkùn tí wọn kò sì ronú ọ̀nà àbáyọ:

> . . . Àwa gọ̀ ní tiwa. Bí a ti pọ̀ tó bẹ́ẹ̀ laa gọ̀ tí a le *mú ọ̀gẹ̀dẹ̀ nínú ọsọ́. Ẹnu ni a fi ń họra.* (Ọmọ Olókùn Ẹṣin p.4)

*'Mú ọ̀gẹ̀dẹ̀ nínú ọsọ́"* àti "*fi ẹnu họra"* gẹ́gẹ́ bí àkànlò èdè Yorùbá, jẹ́ ọ̀rọ̀ apanilẹ́rìn-ín ṣùgbọ́n tí a bá fi ojú ìtumọ̀ àti àkọsílẹ̀ wòó "*fi ẹnu họra"* gbọ́dọ̀ jẹ́ àsọrégèé nítorí

pé ènìyàn kò le gọ̀ gọ̀ gọ̀ kí ó fi ọwọ́, ọmọ-ìka àti èékánná rẹ̀ sílẹ̀ kí ó máa fi ẹnu rẹ̀ họra. Ìtumọ̀ "òmùgọ̀" ni ọ̀rọ̀ yìí ní. Bákan náà ni ó jẹ́ pé ènìyàn kò ní gọ̀ gọ̀ gọ̀ kí ó rí oúnjẹ lórí pàkúté kí ó wá tọwọ́ bọ̀ ọ́. Àkànlò èdè nínú èyí tí a ti rí asọrégèé ni èyí jẹ́ nítorí pé pàkúté ni ọsọ́ jẹ́ àti pé bí Fálétí ṣe lo àwọn ọ̀rọ̀ yìí pa ènìyàn lẹ́rìn-ín gan-an ni.

**3.Ẹ̀ka èdè/èdè àdúgbò**

Ẹ̀ka èdè tàbí èdè àdúgbò jẹ́ ọ̀kan lára èròjà ìdẹ́rìn-ín-pani tí Fálétí máa ń lò nínú iṣẹ́ rẹ̀ láti dá àwọn òǹkàwé rẹ̀ lárayá àti pé ọ̀pọ̀lọpọ̀ iṣẹ́ rẹ̀ ni ó jẹ́ pé èka èdè Ọyọ́ pọ́ńńbélé ni ó fi ṣe àgbékalẹ̀ wọn. Abájọ tí Ọlátẹ́jú (1998) ṣe ṣàlàyé wí pé nígbàkúùgbà tí a bá ṣe àmúlò ẹ̀ka èdè nínú iṣẹ́ ọnà, a máa ń lò ó láti gbé ohun àrà ọ̀tun kan jáde ni èyí sì máa ń jẹ́ kí òǹkọ̀wé rú òfin gírámà. Awọn oníṣẹ́ ọnà tí ó máa ń lo ẹ̀ka èdè máa ń déédé rú ofin gírámà kí wọ́n lè pa àwọn òǹkàwé wọn lẹ́rìn-ín àti dá wọn lárayá ni, ìdí nìyí tí ó fi jẹ́ pé ìṣàmúlò ẹ̀ka èdè Ọyọ́ pọ̀ rẹpẹtẹ nínú iṣẹ́ Fálétí. Lára àpẹẹrẹ àwon ọ̀rọ̀ bẹ́ẹ̀ ni: bá-un, "nù-un," Èéṣe, Èétijẹ́, eléyìí-un, "èyí-un" àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

**4.Àfiwé tààrà**

Lára orísun ẹ̀rín tàbí ọ̀rọ̀ apanilẹ́rìn-ín tí Adébáyọ̀ Fálétí máa ń lò ni ìfọ̀rọ̀yàwòrán. Èyí ni yíya ìṣẹ̀lẹ̀ kan sọ́tọ̀ nínú ìtàn gẹ́gẹ́ bí ohun tí a lè fẹnu sọ, fi etí gbọ́ àti fojú rí nínú iṣẹ́ alákọsílẹ̀ lọ́nà tí yóò fi dàbí ìgbà tí ènìyàn bá ń wo sinimá. Lọ́pọ̀lọpọ̀ ìgbà ni Fálétí máa ń ṣe èyí nínú iṣẹ́ rẹ̀ láti fi pa òǹkàwé rẹ̀ lẹ́rìn-ín àti láti dá wọn lárayá. A rí àpẹẹrẹ èyí nínú "*Ẹ̀dá Kò Láròpin*" nígbà tí Fálétí ń fi ìfọ̀rọ̀yàwòrán ṣe àgbékalẹ̀ ìrora àwọn obìnrin tí ó ru ẹrù tó wúwo tẹ̀lé àwọn ọmọ ìyá méjì tí ìtàn náà dá lé lórí dojú kọ ní ọ̀nà tí ó pani lẹ́rìn-ín báyìí:

> Olúkúlukú ru ẹrù tó tẹ́rù wọ́n ń gbin bí ajá tí egungun ti há l'ẹ́nu (*Èdá Kò Láròpi*n p: 17).

Gbogbo ọ̀rọ̀ òkè yìí ni ó yàwòrán ìṣẹ̀lẹ̀ sí ọkàn òǹkàwé bí ìgbà tí wọ́n ń wo sinimá ṣùgbọ́n èyí tí ó pa ènìyàn lẹ́rìn-ín jù ni àfiwé tààrà tí ó lò láti fi ṣàpèjúwe bí àwọn obìnrin tó ru ẹrù wúwo náà ṣe ń *gbin bí aja tí egungun há lẹ́nu*.

## Ìtúpalẹ̀ Ọ̀rọ̀ Apanilẹ́rìn-ín Nínú Iṣẹ́ Adébáyọ̀ Fálétí

Ṣíṣe àgbéyẹ̀wò orísun ọ̀rọ̀ apanilẹ́rìn-ín nínú iṣẹ́ Adébáyọ̀ Fálétí nìkan kò lè so èso rere láìjẹ́ pé a ṣe àtúpalẹ̀ irú àwọn ọ̀rọ̀ bẹ́ẹ̀ kí á sì mú ìtumọ̀ wọn jáde. Fún ìdí èyi, àtúpalẹ̀ àwọn ọ̀rọ̀ apanilẹ́rìn-ín nínú iṣẹ́ Fálétí yóò dá lórí àwọn orísun ọ̀rọ̀ apanilẹ́rìn-ín tí a ti mẹ́nu bà sẹ́yìn. Lára àwọn orísun ọ̀rọ̀ apanilẹ́rìn-ín náà ni:

### a. Àfiwé tààrà

Gẹ́gẹ́ bí a ti sọ tẹ́lẹ̀, àfiwé jẹ́ ọ̀kan gbòógì lára orísun ọ̀rọ̀ àwàdà tàbí apanilẹ́rìn-ín nínú iṣẹ́ Adébáyọ̀ Fálétí. Nínú ewì "*Adébímpé Ọjẹ́dòkun*," Fálétí ṣe àmúlò àfiwé tààrà láti fi ṣe àpèjúwe ojo ọdẹ tí ó yin ìbọn lu Adébímpé Ọjẹ́dòkun dípò ẹkùn ní ọ̀nà tí ó panilẹ́rìn-ín báyìí:

> Ọdẹ ò tètè mọ̀ p'ẹ́kùn ò le jà

*Ọdẹ ń gbọ̀n rìrì bí arúgbó dami nù l'ójú òde*

Ǹjẹ́ ọdẹ má gbọ̀n mọ́

Tan'ná ràn'bọn" rẹ o jẹ́ ká lọ

À fi kàrò! t'íbọn dáhùn lọ́wọ́ ọdẹ a-gbọ̀n-bí-ọ̀gà

Àpẹẹrẹ àyọlọ̀ òkè yìí kò lè ṣe kí ó má panilẹ́rìn-ín, pàápàá jùlọ fún ẹni tí ó bá ti rí àgbàlagbà tó ti darúgbó rí níbi tí ó ti fẹ́ da nǹkan nù láti inú ilé sí gbàgede ìta. Fún ìdí èyí lílo àfiwé tààrà gẹ́gẹ́ bí ọ̀rọ̀ àwàdà láti ṣe àpèjúwe àti àfiwé bí ọwọ́ ọmọ ọdẹ tó fẹ́ yìnbọn sí ẹkùn ṣe ń gbọ̀n pẹ̀lú ọwọ́ arúgbó tí ó ń gbọ̀n nítorí ọjọ́ ogbó nígbà tí ó fẹ́ da omi nù lóde gbọ́dọ̀ pa èniyàn lẹ́rìn-ín. Bákan náà, nínú àyọlọ̀ òkè yìí, ọ̀rọ̀" ìsọdorúkọ," *A-gbọ̀n-bí-ọ̀gà"* èyí tí ó ń ṣ'àpèjúwe gbígbọ̀n-rìrì àti ìwà ojo tí ọdẹ náà hù tún jẹ́ ohun tí ó pa èniyàn lẹ́rìn-ín jọjọ. Gbígbọ̀n tí arúgbó ń gbọ̀n nígbà tí ó fẹ́ da omi nù lójú òde wáyé nítorí pé gbogbo iṣan ọwọ́ rẹ̀ ni ààrẹ̀ ti mú nítorí ọjọ́ ogbó nígbà tí gbígbọ̀n ọmọ ọdẹ wáyé nítorí ẹ̀rù ẹkùn tí ó ń bà á, ṣùgbọ́n a kò le rẹ́rìn-ín níbi tí ìlú-mọ̀-ń-ká ọdẹ pàtàkì ti ń pọ̀kàkà ikú, èyí tí ojo ọdẹ ṣokùnfà rẹ̀. ìdánilójú rè é wí pé kìí ṣe gbogbo ọ̀rọ̀ apanilẹ́rìn-ín ni èèyàn gbọ́dọ̀ rẹ́rìn-ín sí àti pé, tí a bá rẹ́rìn-ín, a rẹ́rìn-ín nítorí pé kò kàn wá gbọ̀ngbọ̀n ni tàbí kó jẹ́ pé a kò tan mọ́ ẹni tí ọ̀rọ̀ kàn. Irú ọ̀rọ̀ apanilẹ́rìn-ín báyìí ń jẹ́ kí àwọn òǹkàwé túraká kúrò nínú jìn-nì-jìn-nì ìbànújẹ́ tí ìtàn náà mú jáde bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé kò sí ohun tí ẹnikẹ́ni lè ṣe láti yí àkọsílẹ̀ tàbí àyànmọ́ Adébímpé Ọjẹ́dòkun padà. Ọ̀rọ̀ apanilẹ́rìn-ín náà ń ṣe àfihàn ìbànújẹ́ àti ayọ̀ èyí tí ọ̀rọ̀ ayé tí a wà nínú rẹ̀ yìí dá lórí. A tún lè sọ pé ìṣàmúlò irú ọ̀rọ̀ apanilẹ́rìn-ín báyìí tàbùkù ọmọ ọdẹ tí a lò ó fún ṣùgbọ́n a tún rìi pé kí á fi ọ̀rọ̀ tàbùkù ọdẹ yìí kò ní èèwọ̀ nítorí ìwà ojo rẹ̀ àti pé ìtàbùkù yìí gan-an ni ó mú ẹ̀rín wá.

Nínú ewì "*Ìgbéyàwó Kan Ní Ìletò Wa,"* a rìi bí ẹ̀rín ṣe gbọn èniyàn lẹ́kún níbi tí a ti lo àfiwé tààrà pẹ̀lú ìfọ̀rọ̀yàwòrán-ojú-sọ́kàn-ẹni nínú àdánwò ńlá tí ọmọ ẹ̀dá bá ara rẹ̀. A lè rí àpẹẹrẹ èyí níbi tí a ti ṣe àpèjúwe Àkàndé nígbà tí ó fẹ́ bọ́ sí gbàgede láti jó:

Ni ó bá wá mú ìborùn kan ńlá

Ó yíi mọ́'rí tutu bí *ẹlẹ́hàá lèmọ́-ọ́n-mù ahéré wa*

Ó tún m'áṣọ ó fi bora

Gbogbo rẹ̀ wá *wú pàmù bíi láwànì ìjòyè*

Nínú àpẹẹre òkè yìí, a ri pé ìmúra kò-báṣà-mu Àkàndé àti àfiwé tààrà tí ó tẹ̀lé ì-fọ̀rọ̀-yàwòrán-sọ́kàn-ẹni mú ẹ̀rín tí ó gbópọn jáde. Lóòótọ́, a lè gbìyànjú láti rẹ́rìn-ín ṣùgbọ́n nígbà tí a bá rántí pé aláàánú àti onínúrere abúlé kan tí ó ń gbìyànjú láti wá wọ̀rọ̀kọ̀ fi ṣ'àdá lórí àdánwò burúkú tí ó wà ní sàkáání rẹ̀ ni ọ̀rọ̀ yìí kàn, ẹ̀rín yóò gbẹ mọ́ wa lẹ́nu. Kò fi bẹ́ẹ̀ sí ìyàtọ̀ nínú ohun tí a sọ yìí àti àpèjúwe àgbékalẹ̀ ijó Àkàndé:

Tí wọ́n ḿ b'Ákàndé yíìká ọrùn kọ́íkọ́í

Bíi pẹ́pẹ́yẹ ṣ'àníyàn ara wọn

……………………………………………………..

> Bí gẹ̀gẹ̀ ti ń lọ tí ḿbò lọ́rùn afínjú oko wa
>
> Gẹ̀gẹ̀ tí ń ta bọ̀n-ùn, *bí ẹwìrì Ògúnlànà*

Ọ̀rọ̀ àfiwé tí ó mú ẹ̀rín jáde nínú ìsọ òkè yìí ni "*bíi pẹ́pẹ́yẹ ṣàníyàn ara wọn.*" Ìwọ̀n ìba àwọn tí ó bá ti rí pẹ́pẹ́yẹ níbi tí wọ́n ti péjọ láti mu omi tàbí tí wọn ń káárà-mááàṣìkí ara wọn nígbà tí ọ̀kan nínú wọn bá wà nínú ewu nìkan ni ó lè rẹ́rìn-ín. Bákan náà ni ó jẹ́ pé bí a ṣe lo ọ̀rọ̀ ìṣe "*yûká*" àti ọ̀rọ̀ àpọ́nlé "*kọ́íkọ́í*" pani lẹ́rìn-ín jọjọ nítorí pé ó ṣe àgbéjáde tàbí àfihàn ìfọ̀rọ̀-yàwòrán-inú sí ọkàn ènìyàn èyí tí ó tẹ̀lé àfiwé tí ó sì jẹ́ kí ó dàbí ẹni pé ìṣẹ̀lẹ̀ náà ń ṣẹlẹ̀ lọ́wọ́lọ́wọ́ lójú ẹni. Iṣẹ́ tí a fi àwọn ọ̀rọ̀ apanilẹ́rìn-ín yìí ṣe ni láti tu ọkàn àwọn òǹkàwé lára àti láti jẹ́ kí ìkáyàsókè àti jìnnìjìnnì tí ó bò wọ́n nítorí làásìgbò tí Àkàndé onínúrere ń dojú kọ wálẹ̀ díẹ̀.

Ọ̀rọ̀ apanilẹ́rìn-ín tí a fi àfiwé tààrà àti mẹ́táfọ̀ gbé kalẹ̀ tún jẹyọ nínú *Ogun Àwítẹ́lẹ̀* níbi tí olórí àwọn ọdẹ àti ọ̀kan lára àwọn ọmọ olè ti ń wọ̀yá ìjà:

> Nígbà tí ìtọ̀sẹ̀ dùn ún, *ó ké mẹ̀ẹ́ẹ̀ bí ẹran,* ṣùgbọ́n kí ó tó pa ẹnu náà dé, mo gbá a ní ìgbò ní imú, àmúrun sì sẹ́ ní imú rẹ̀. Síbẹ̀ n kò fi gògòńgò *alákọrí* yìí sílẹ̀. Mo fún un daindain. Níkẹyìn sá, tèmi sẹ́ tirẹ̀, mo sì sọ a-wọn-ni-síhòòhò náà di *ẹran Ògún*

Tí a bá wo àyọkà òkè yìí dáadáa, ẹ̀rín kò lè má pa ènìyàn níbi tí ògbójú ọlọ́sà ti ń ké "*mẹ̀ẹ́ẹ̀*" bí ẹran lẹ́yìn tí ọwọ́ ìyà ti bà á dáadáa. Fìrósínrọ̀ójé "*mẹ̀ẹ́ẹ̀*" ni ẹyọ ọ̀rọ̀ àkọ́kọ́ tí a lò gẹ́gẹ́ bí ọ̀rọ̀ apanilẹ́rìn-ín tí a lè fi etí wa gbọ́ kí ó tó wá kan "*bí ẹran*" tí ó jẹ́ àfiwé tààrà tí òun náà pa èniyàn lẹ́rìn-ín. Yàtọ̀ sí èyí, àwọn ẹyọ ọ̀rọ̀ bíi "*Alákọrí*" àti "*a-wọ́n-ni-síhòòhò* tí a fi "ìsọdorúkọ" gbé kalẹ̀ pẹ̀lú "*ẹran Ògún*" èyí tí í ṣe mẹ́táfọ̀ kò lè má panilẹ́rìn-ín nítorí ọ̀nà tí a gbà lò wọ́n láti dúró fún olè tàbí ìgárá ọlọ́sà. Àwọn ọ̀rọ̀ apanilẹ́rìn-ín tí a lò wọ̀nyí ṣe àfihàn olè tàbí ìgárá ọlọ́sà gẹ́gẹ́ bí ẹni ẹ̀kọ̀ láwùjọ.

Ìlò àfiwé tààrà gẹ́gẹ́ bí ọ̀rọ̀ apanilẹ́rìn-ín tún farahàn nínú *Ọmọ Olókùn Ẹṣin* níbi tí a ti fi ìrísí Àjàyí wé ìrísí ẹni tí ó ru iwọ lẹ́yìn tí ó bá Rótì jà tí ó sì ṣẹ́gun rẹ̀:

> Àwọn ẹ̀gbọ́n mi tí a jọ lọ bá wọn pa koríko bẹ̀rẹ̀ sí sunkún. Ní tèmi, *ranran ni ojú mi le bí ojú ẹni tí ó ru iwọ*

Nínú àyọlọ̀ òkè yìí, ọ̀rọ̀ tí ó jẹ́ fìrómọ̀rísí – "*ranran*" àti àfiwé "*bí ojú ẹni tí ó ru iwọ*" tí ó tẹ̀lé e ni àwọn ọ̀rọ̀ tí ó pa ènìyàn lẹ́rìn-ín nínú àyọlọ̀ náà. Ó jẹ́ ohun tí ó pani lẹ́rìn-ín láti ṣàpèjúwe ìrísí Àjàyí bí ìrísí ẹni tí ó ru iwọ. A lè rẹ́rìn-ín à rín tàkìtì níbí nítorí pé a mọ̀ pé ìjà ẹ̀tọ́ ni Àjàyí ń jà nígbà tí àwọn ọ̀tá rẹ̀ sì rí i gẹ́gẹ́ bí ẹhànnà ọmọ tó fẹ́ dojú àṣà "bolẹ̀." Ọ̀rọ̀ apanilẹ́rìn-ín yìí ṣe àfihàn Àjàyí gẹ́gẹ́ bí ẹni tí ó ti pinnu lọ́kàn rẹ̀, tí kò sì bìkítà lórí ohunkóhun tí ó lè ti ẹ̀yìn ìwà ajìjàgbara tí òun ń hù jáde.

Nínú *Wọ́n Rò Pé Wèrè Ni* a rí àpẹẹrẹ àfiwé tààrà tí a lò gẹ́gẹ́ bí ọ̀rọ̀ apanilẹ́rìn-ín níbi tí Ọmọ́mọṣẹ́ olórin ti ń fi eré rẹ̀ dá àwọn ènìyàn lárayá ní Ọjà Ọba:

> Ọmọ́mọṣẹ́: Ẹ farabalẹ̀ o!
>
> Ègbè: A ti farabalẹ̀ tẹ́lẹ̀tẹ́lẹ̀ k'óo tó wí bígi-imú onídàrùké ti í farabalẹ̀ f'óòòrùn

Ènìyàn kò lè s.àìrẹ́rìn-ín sírú àfiwé báyìí nítorí ìsewẹ́kú ohun méjì tí a fi wé ara

wọn. Onídàrùké kò lè ṣe kí ó má tẹ́ imú rẹ̀ sí abẹ́ òòrùn nítorí pé bí kò bá parí iṣẹ́ òòjó rẹ̀ tí ó gbà nínú oko, kò lè kúrò nínú òòrùn. Ó rọrùn fún Ọmọ́mọṣẹ́ àti àwọn ẹlẹgbẹ́ rẹ̀ láti fi àfiwé yìí dá àpárá nítorí pé wọ́n ní oore ọ̀fẹ́ láti máa ṣeré ní ọwọ́ ìrọ̀lẹ́ níbi tí ará ti tù wọn àti àwọn tí wọn ń ṣeré fún àti pé alágbe ni Yorùbá mọ̀ wọ́n sí, iṣẹ́ wọn kò sì nira bíi ti àwọn onídàrùké tàbí alágbàṣe oko tí ó ń ṣiṣẹ́ láti òwúrọ̀ nínú òòrùn àti òjò láìsinmi títí tí wọn yóò fi parí iṣẹ́ ọjọ́ náà.

**b. Ìfọ̀rọ̀dárà**

Ìfọ̀rọ̀dárà ni Salvatore (2018), pè ní fifi ìró ẹyọ ọ̀rọ̀ kan dárà nínú iṣẹ́ ọnà ní ọ̀nà tó jẹ́ pé ìṣewẹ́kú ìró wàyé ní ìbámu pẹ̀lú àwọn ìró tó tún tẹ̀lé ìró ọ̀rọ̀ tí akọ́kọ́ fi dárà ní ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀. Tí irú èyí bá wáyé, ìtẹnumọ́, àwàdà tàbí ẹ̀rín rínrín ni yóò jẹ́ àbájáde irú iṣẹ́ ọnà bẹ́ẹ̀. Nínú iṣẹ́ Adébáyọ̀ Fálétí, a rí àpẹẹrẹ ìfọ̀rọ̀dárà. Fálétí lo àwọn ọ̀rọ̀ apanilẹ́rìn-ín yìí láti ṣe àpọ́nlé àti tàbùkù àwọn akópa kan ni. Bi àpẹẹrẹ, nínú *Baṣọ̀run Gáà,* a rí akópa kan tí ó ń jẹ́ Ìyá Ilé Orí níbi tí ó ti ń fi orúkọ "Akínkúnmi" dárà ní ọ̀nà tí ó mú àwàdà lọ́wọ́ tàbí panilẹ́rìn-ín ṣùgbọ́n tí ó tàbùkù ẹni tí a ń fi orúkọ rẹ̀ dárà. Ó ṣe èyí láti jẹ́ kí ìfẹ́ Akínkúnmi yọ kúrò ní ọkàn Àgbọ̀nyín nítorí pé akúṣẹ̀ẹ́ ni Akínkúnmi kò sì wá láti ìdílé ọlọ́lá bíi ti Àgbọ̀nyín tí ó jẹ́ ọmọ ọba:

Ìya Ilé Ori: Dákẹ́, k'o jẹ́ n gbọ́rọ̀

Má jẹ̀ẹ́ kí n ṣì wí sọ́rọ̀ rẹ!

Ta l'ajá tíí *j'Ákínkúnmi*?

B'óo bá ń gbọ́ tí wọ́n ń *p'Akin* lọ níwájú

B'óo bá ń gbọ́ tí wọ́n ń "*p'Akin* bọ̀ lẹ́yìn

À fi k'énìyàn ó wolẹ̀ lọ́rọ̀ *Akin* kó tó *b'Ákin* ṣe
*Akín*kúnmi lásán ò tó fẹ̀yìn tì
À fi bá a gbọ́kàn lé "rú àwọn *Akín*dúrótini
B'ó o bá bímọ má sọ ọ́ l'*Ákín*wùmí
Ẹni tó s'ọmọ *l'Ákín*wùmí, ẹ̀bẹ̀ ló ń bẹ̀
*Akin*-wù-wọ́n lásán ni, àwọn kìí níwà *Akin*
Ẹni tó s'ọmọ l'*Ákin*labí
Wọ́n ń fẹnu polongo *Akin* lásán ni
*Akín*délé ń wínkùn
*Akín*yẹlẹ́ ń ṣàrò̀yé
Wọ́n ń sọ p'áwọn ò kọ́lé
Ẹ̀ bá bèèrè pé kí l'*Akin* wọn rí mú bọ̀ látìta?
Ènìyàn tó ń jẹ́ *Akín*yẹmí
Ó ń dára rẹ̀ nínú dùn ni
Ẹni tó lówó lohun gbogbo yẹ
Kín l'*Akin* jẹ́ b'*Ákin* ò lọ́lá?
Kín *l'Akin* jẹ́ b'*Ákin* ò níyì?
*Akin* tí ò lọ́lá, *Akin* tí ò débìkan ni
Òun l'ẹni tó bá gbọ́n fií s'ọmọ lórúkọ tó dára
Wọn a s'ọmọ l'*Ákín*tọ́lá, *Akin*ọlá, *Akin*bọ̀bọ́lá
*Akin*-mi-bọ̀-bọ́lá
Ọlá mi y'*Akin* àbí kò y'*Akin*? Ọlá*yakin*

*Akin* tá a bá f'ọlá kún l'*Akin* tó péye

Ohun tí ó panilẹ́rìn-ín nínú àyọlò òkè yìí ni ọ̀nà àrà ọ̀tọ̀ tí Fálétí gbà láti fi orúkọ *Akin* dárà láti ìbẹ̀rẹ̀ títí dé òpin. Ó fi orúkọ "Akínkúnmi" ṣe yẹ̀yẹ́ nípa lílo "ìbéèrè pèsìjẹ" bíi "Ta l'ajá tíí j'Ákínkúnmi'?, "Kín l'Akin jẹ́ b'Ákin ò lọ́lá?," Kín l'Akin jẹ́ b'Ákin ò níyì?." Fálétí fi orúkọ *Akin* dárà títí tí ó fi fa àwọn oríṣìí ìtumọ̀ kan tí ó jinlẹ̀ èyí tí a kò mọ̀ mọ *Akin* tẹ́lẹ̀ jáde lọ́nà tí ó panilẹ́rìn-ín tí ó tún jẹ́ kí á mọ̀ wí pé àwọn orúkọ *Akin* kan wà tí ó ṣe pàtàkì tàbí wúlò ju àwọn *Akin* mìíràn lọ. Irú ìṣàmúlò ìfọ̀rọ̀dárà yìí wà fún fifi ẹnu tẹ́ḿbẹ́lú tàbí yẹpẹrẹ Akínkúnmi ẹni tí ó nífẹ̀ẹ́ Àgbọ̀nyín ṣùgbọ́n tó jẹ́ pé ọmọ akúṣẹ̀ẹ́ ni. Lílo àfiwé ẹlẹ́lòó "*ta l'ajá tó ń jẹ́ Akínkúnmi?*" gan an ni ìpèdè tí ó tàbùkù Akínkúnmi tí ó sì tún pa ènìyàn lẹ́rìn-ín jùlọ. Ìyá Ilé Orí rí ìdí pàtàkì tí òun kò fi lè gbà kí Àgbọ̀nyín ọmọ ọba fẹ́ Akínkúnmi tí àwọn òbí rẹ̀ kò jẹ́ nǹkan kan ní àwùjọ. Yàtọ̀ sí pé ó wá láti ìdílé òtòṣì, orúkọ rẹ̀ (Akínkúnmi) tún dúró fún òṣì nítorí pé kò ní "Ọla" nínú àti pe àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé orúkọ a máa ro ènìyàn gẹ́gẹ́ bí Ìyá Ilé Ori ṣe nígbàgbọ́ pé "*Akin" tí ò ní "Ọlá" nínú jẹ́ Akin yẹpẹrẹ*. Àwọn oríṣìí ìtumọ̀ *Akin* tó tàbùkù Akínkúnmi tí ìyá yìí fà jáde pa ènìyàn lẹ́rìn-ín ṣùgbọ́n nígbà tí a bá rántí pé ènìyàn kan ni ó bí Akínkúnmi àti pé bí a ṣe bí ẹrú náà ni a ṣe bí ọmọ, ènìyàn kò ní fẹ́ láti rẹ́rìn-ín.

### d. Èdè Àdúgbò/Ẹ̀ka Èdè

Èdè àdúgbò tàbí ẹ̀kà èdè Ọyọ́ tí Fálétí ń lò nínú àwọn iṣẹ́ rẹ̀ máa ń dẹ́rìn-ín pa àwọn òǹkàwé rẹ̀ lọ́pọ̀lọpọ̀ ìgbà nítorí ìyapa wọn sí èdè àjùmọ̀lò. A rí àpẹẹrẹ irú èyí nínú *Wọ́n Rò Pé Wèrè NI* níbi tí Bàbá àti Olóókọọba ti ń sọ̀rọ̀ nípa ọ̀rẹ́ tí Àrẹ̀mú àti Bàbá Rámọ̀ ń ṣe.

> Bàba: Bàbá Rámọ̀ ló ń jẹ́ Ládépò o, Àrẹ̀mú ló wá ń bọ́ Bàbá Rámọ̀ tó ń fún un lówó, tó ń fún un lóńjẹ ǹ jẹ́ ọ̀rẹ́ "*èyí-un*" kò pọ̀ "*báun*"?
>
> Olóokọọba: Háà, ọ̀rẹ́" re *nù-un*

Ìtàkurọ̀sọ òkè yìí pani lẹ́rìn-ín nítorí àwọn èdè àdúgbò Ọyọ́ tí a lò bíi "*èyí-un" "báun"* àti "*nù-un."* A lò wọ́n láti tẹpẹlẹ mọ́ nǹkan ni. Nǹkan tí a tẹpẹlẹ mọ́ náà ni "ọ̀rẹ́ rere." Láti lè lo èdè àdúgbò yìí fún ìpanilẹ́rìn-ín, ìyapa tí ó máa ń jẹ́ kí irú àwọn ọ̀rọ̀ báyìí pàkíyèsí ara wọn sí òǹkàwé nínú ìwé kìká tàbí ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ tó jẹ́ tí èdè ojúmọ́ wáyé. Ìyapa yìí máa ń jẹ́ kí àwọn ẹ̀ka èdè tàbí èdè àdúgbò báyìí ṣàjèjì sí àwọn òǹkàwé ni. Bí àwọn ẹ̀ka èdè yìí ṣe ṣàjèjì sí wa yìí, tí wọ́n sì tuntun lójú wa gan-an ni ó ń ṣokùnfà ẹ̀rín. Bí àpẹẹrẹ, tí kò bá sí ìyapa, tí a sì fi èdè àjùmọ̀lò kọ àwọn èdè àdúgbò tí a lò lókè yìí, àwọn ọ̀rọ̀ bíi *"èyí-un" yóò di "ìyẹn/èyí"* "*báun" yóò di "báyẹn/báyìí"* nígbà tí "*ọ̀rẹ́ re" yóò di "ọ̀rẹ́ ire"* láìpa ìró fáwẹ̀lì (i) jẹ, wọ́n sì tún lè má pa ènìyàn lẹ́rìn-ín. Ìpàrójẹ yìí wáyé fún gígé ọ̀rọ̀ kúrú ni.

### e. Ìfọ̀rọ̀yàwòrán

Lábẹ́ àkóórí yìí ni a ti ń mú kí àwọn òǹkàwé máa wo ìran ìṣẹ̀lẹ̀ tí wọ́n yóò sì tún gbọ́ ohun tí àwọn akópa ń sọ nínú iṣẹ́ Adébáyọ̀ Fálétí. Èyí máa ń ṣeéṣe nípa ọ̀nà tí Fálétí ń gbà lo èdè lọ́nà tí yóò ya àwòrán ìṣẹ̀lẹ̀ sí ojú àti ọkàn òǹkàwé. Fálétí máa ń lo èdè láti ṣàlàyé ìṣẹ̀lẹ̀ ní kíkún fún àwọn òǹkàwé rẹ̀. A rí àpẹẹrẹ irú èyí tó panilẹ́rìn-ín níbi tí Àkàndé ti ń jó tí gẹ̀gẹ̀ ọrùn náà ń jó pẹ̀lú rẹ̀.

L'Àkàndé bá pòyì ràn-ìn, l'ó wọ́n'ṣọ lọ́rùn bóróbó

Ní ó tún ta pẹẹrẹ bọ́ sínú agbo

B'Ákàndé bá na ọrùn síwájú, á tún na ọrùn sẹ́yìn

B'ó bá rin àrìnjó títí

Á yọrí síwájú, á y'ọrí sẹ́yìn bí ògòǹgò babe ẹyẹ

B'ípàkọ́ ti ń fì dùgbẹ̀ lẹ́yìn

Orúbandú tí ḿ bẹ lọ́rùn a sì yọ síwájú bọbọbọ

Àyọlò òkè yìí jẹ́ èyí tí Fálétí yà sọ́tọ̀ láti yàwòrán ojú sí ọkàn àwọn òǹkàwé àti láti jẹ́ kí wọ́n máa gbọ́ ohun tí ó ń ṣẹlẹ̀ sí etí wọn. Àwọn ọ̀rọ̀ bíi "*pòòyì rain-in*" "*wọ́n sọ lọ́rùn bóróbó*" "*ta pẹẹrẹ,*" "*ń fì dùgbẹ̀ lẹ́yìn,*" "*síwájú bọbọbọ*" tí wọ́n jẹ́ "fìrómọ̀rísí" àti ọ̀rọ̀ bíi "*òrúbandú,*" "*bí ògòǹgò baba ẹyẹ*" tí wọ́n jẹ́ "àfiwé elẹ́lọ̀ọ́" àti "àfiwé tààrà" alápèjúwe ni Fálétí lò fún ìyàwòrán s'ójú, sọ́kàn òǹkàwé àti gbígbọ́ ọ̀rọ̀ àwọn akópa lọ́nà tí ó panilẹ́rìn-ín jọjọ. Ìwúlò irú ìṣàmúlò èdè báyìí ń jẹ́ kí òǹkàwé máa rí ìṣẹ̀lẹ̀ lójúkojú nínú ìwé kíkà èyí yóò sì jẹ́ kí wọ́n tètè rántí ohun tí wọ́n kà láti ọjọ́ pípẹ́.

A tún rí àpẹẹrẹ ìfọ̀rọ̀yàwòrán sí ojú àti sí ọkàn òǹkàwé tí ó panilẹ́rìn-ín nínú *Alágbára Ilé àti Alágbára Oko II* níbi tí Adédigba (Alágbára ilé) ti fojú kan kàyééfì alágbára oko nílé onítòhún:

B'Álágbára ilé ti tún rí kàyééfì yìí

*Ó ṣe bí ẹni fẹ́ tọ̀ l'ẹ́yìnkùlé*

*Ó yára gb'ẹ́sin rẹ̀ kọ́rùn*

*Ó ń sá lọ bẹ́ẹ̀ ni kò dẹ̀rìn,* ó ní

Alágbára oko ju Alágbára-ilé lọ.

Ìsọ òkè yìí kò lè má pa ènìyàn lẹ́rìn-ín, nígbà tí a bá rí alágbára ilé tí ó sọ pé òun ni ó lágbára jù bá fẹsẹ̀ fẹ́ẹ lọ́gán tí ó rí kàyééfì agbára alágbára oko. Àwọn àpólà ìṣe tàbí ọ̀rọ̀ tí ó pani lẹ́rìn-ín ni "*sá lọ bẹ́ẹ̀ ni kò dẹ̀yìn,*" àti ọ̀rọ̀ arọ́pò orúkọ ẹnikejì "*O*" tí a lò pẹ̀lú oríṣìí ọ̀rọ̀-ìṣe bíi "*ṣe*" "*ń sá lọ*" pẹ̀lú àfiwé tààrà "*bí ẹni fẹ́ tọ̀ lẹ́yìnkùlé.*" Gbogbo àwọn ọ̀rọ̀ yìí ni ó ṣe àfihàn agbára alágbára oko ní ọ̀nà tí ó pa ènìyàn lẹ́rìn-ín tí ó sì tún gbé ìṣèlè náà síwájú òǹkàwé bí ìgbà tí ó ń ṣẹlẹ̀ lọ́wọ́lọ́wọ́ níwájú wọn.

## Àgbálọgbábọ̀

A ti ná ìgbárá, a sì ti ná ìgboro lórí àwọn ọ̀rọ̀ àwàdà tàbí apanilẹ́rìn-ín nínú iṣẹ́ Adébáyọ̀ Fálétí. A ti jẹ́ ká mọ̀ pé káríayé ni ọ̀rọ̀ ẹ̀rín rínrín jẹ́ àti pé níbikíbi tí a bá ti lo ọ̀rọ̀ apanilẹ́rìn-ín, ó di dandan kí á rẹ́rìn-ín; ó kàn jẹ́ pé kìí ṣe gbogbo ìṣẹ̀lẹ̀ tí ó panilẹ́rìn-ín ni a le rẹ́rìn-ín śi ni. Àrídájú tí a tún ní ni pé Adébáyọ̀ Fálétí yege nípa lílo ọ̀rọ̀ apanilẹ́rìn-ín fún ìpèníjà, ìkìlọ̀ ìwà ìbàjẹ́ tàbí àìsòótọ́ àti dída òróró ìtura sí ojú ọgbẹ́ àwọn tí ayé ti ṣa lọ́gbẹ́ ní àwùjọ wa. Èyí fara hàn púpọ̀ lórí bí ó ṣe lo ọ̀rọ̀ apanilẹ́rìn-ín nínú ọ̀pọ̀lọpọ̀ iṣẹ́ rẹ̀ àti pé èyí gan-an ló mú kí Ọlátúnjí (1986:2) sọ pé àjogúnbá ni àṣà pípanilẹ́rìn-ín jẹ́ fún Fálétí. Ju gbogbo rẹ̀ lọ, bébà yìí tún ṣe àfihàn pé "erẹ ni a máa ń fi ọmọ ayò ṣe" àti pé ìdárayá ni ohun àkọ́kọ́ tí ó jẹ Fálétí lógún nínú àwọn iṣẹ́ rẹ̀ kí ó tó kan ìdánilẹ́kọ̀ọ́, ìdí nìyí tí ọ̀rọ̀ apanilẹ́rìn-ín ṣe jẹ́ pàtàkì fún un láti dá àwọn òǹkàwé rẹ̀ lárayá. Nípa lílo ọ̀rọ̀ apanilẹ́rìn-ín, Fálétí kọ́ wa bí a ṣe

lè dojú kọ ìṣòro tó bá dojú kọ wá láwùjọ wa láìkáyà sókè. Lóòótọ́, ọ̀rọ̀ apanilẹ́rìn-ín tàbí ọ̀rọ̀ àwàdà kò dá dúró gẹ́gẹ́ bí ẹ̀yà lítíréṣọ̀ ṣùgbọ́n Fálétí gbìyànjú tirẹ̀ láti ṣe àmúlò rẹ̀ nínú ọ̀pọ̀lọpọ̀ iṣẹ́ rẹ̀ dé ibi tó lápẹẹrẹ fún ìwúlò ọmọ adáríhunrun.

## ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ


Askenasy, J.J.M (1987), The function and dysfunction of laughter. *Journal of General Psychology*, 114, 317-334.

Berlyne, D.E (1969), Laughter, Humour and Play. G. Landzey and E. Aronson (eds), *The Handbook of Social Psychology*, 3: 795-852. Reading, M.A Addison-Wesley.

Chapman, A.J (1976), Social aspects of humour laughter. T. Chapman in and H. Foot (eds) *Humour and Laughter: Theory, Research and Application* (pp. 155-185) London: Wiley.

Darwin, C. (1972), *The Expression of the Emotions in man and Animals* (3rd ed). London: HarperCollins.

Fálétí, A. (1980), *Wọ́n Rò Pé Wèrè Ni*, Ìbàdàn, University Press Ltd.

Fálétí, A. (1979), *Ogun Àwítẹ́lẹ̀*, Ìbàdàn, University Press Ltd.

Fálétí, A. (1972), *Baṣọ̀run Gáà*, Ìbàdàn, Onibonoje Press.

Fálétí, A. (1969), *Ọmọ Olókùn Ẹṣin,* London, University of London Press.

Hirson, A. (1995), Human laughter: a forensic phonetic perspective. *Beiphot*, 64, 77-86.

Ọlábọ̀dé, A. (1981), The semantic basis of metaphors and related troops in Yoruba. PhD thesis, University of Ìbàdàn.

Ọlátẹ́jú, A. (2005), The Yorùbá animal metaphor: analysis and interpretation. *Nordic Journal of African Studies* 14/3: 368-383

Ọlátúnjí, O. (1984), *Adéjọkẹ́ Ará Ìjílèje: Àkójọpọ̀ Ìtàn Adébáyọ̀ Fálétí*, Ìbàdàn: Heinemann Educational Books.

Provine, R.R. (1969), "Laughter," *American Scientist*, 84,38-45.

Ruch, W. (1993), Exhilaration and Humour. M. Lewis and J.M Haviland (eds). *Handbook of Emotions* (1st ed. Vol. 1 pp. 605-616). New York. Guilford Press.

Ruch, W. and Ekman, P. (2001), "The Expressive Pattern of Laughter" M.A Kaszniak (eds) *Emotion, Qualia, and Consciousness* (pp. 426-443) Tokyo: word Scientific.

Salvatore, A. (2018), *Cultures and Traditions of Wordplay and Wordplay Research*, Texas, A&M University College Press, 89-110.

Taiwo, H. (2017), From conceptual metaphor: metaphorical language in Yorùbá proverbs and praise poems. *Journal of Language Matters/Studies in the Language of Africa,* 48(3): 130-144.